**Akiyesi**

A nfẹ awọn enia ti yio ma ba wa ta Irohin Imọlẹ ni awọn ilu wọnyi. Igbo-Ọra Shaki Iṣẹyin Eruwa Lalate AkurẹOndo Ado- Ekiti Gbogan Fiditi Oyo. Ẹdẹ Ikorodu Shagamu Ilaro ati Ilora.

E kowe si:-
Olotu IROHIN IMỌLẸ
16, Bamgbose Street,
Lagos.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye Oro**

Agboju logun fara rẹ fun oṣi ta ẹniti k o ṣiṣẹ yẹ ko jẹun, m a se ba oni binu enia ẹgbẹ po, bẹni ki o maṣe boojnu fufu rin eni to ngbowo ẹhin o nyọ ra rẹ lẹnu, ma ṣe fẹran o r u n sisun ki iwọ maba di alaini nitoripe igbẹhin lo ndun oloku ada.

VOL. VI No. 329 MONDAY MAY 14 — MAY 20 1962 KỌBỌ MEJI (2)

# GUDUGBẸ GUDUGBẸ, IJA KAN NBỌ

## Akintọla ati Awolọwọ, kitigbe! Ẹfun mbedi?

A TUN NGBỌ FẸRẸN-FẸRẸN PE IJA YIO TUN BẸ SILẸ NINU ẸGBẸ AFẸNIFẸRE TI AWỌN OLORI ẸGBẸ KO BA YI IWA WỌN PADA SI ARA WỌN. TI EYI BA ṢẸLẸ YIO JẸ IGBA KEJI LARIN OṢU KẸTA TI IJA YIO BẸ SILẸ LARIN A. G.

A gbọ wipe Oloye Akintọla, Olotu Ijọba Iwọ Orun ẹniti nṣe igbakeji Oloye Awolọwọ Baba ẹgbẹ A. G. jake jado gbogbo aiye ti paṣẹ fun ọkan ninu awọn Minista rẹ, Ọgbẹni Kesington Mọmọ wipe ki o ṣo atunṣe yiyan enia si ibiṣẹ Ijọba ti Development Corporation.



Oloye S. L. Akintola

Lẹhin ija ti akọkọ ni iṣẹ bọ lọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ bi Ọgbẹni Ọdẹku ti o duro pari ipade ni Jos ti o si d igbakeji Akọwe.

Lati igbati ija ti bẹ silẹ ni Jos ni Oloye Akintọla ati Oloye Awolọwọ ko ti dan to bẹ mọ. Bi o si tilẹ jẹ pe nwọn pari ija na fun wọn, apa ko jọ ibi ara mọ.

Oloye Awolọwọ ni bi aṣọ ti Oloye Akintọla pa ba ṣe nipa pe ki nwọn ṣe atunṣe yiyan enia sibi iṣẹ Development Corporation, on na yio lo aye on gẹgẹbi baba ẹgbẹ A G lati ṣe atunṣe yiyan minista silẹ igbimọ. Ibadan

Ọgbẹni Samu Ikoku, Akọwe ẹgbẹ Ọlọpẹ niha ila orun fi ẹsun sun Oloye Akintọla wipe, on li ẹniti o nda mọdaru si arin meji ẹgbẹ Ọlọpẹ.

Nisisiyi o dabi ẹni pe awọn mejeji ti ba nkan pupọ jẹ ti o jẹ wipe nkan na ko le ṣe tunṣe kiakia. A gbọ pe awọn ti o jẹ alatilẹhin fun Oloye Awolọwọ fẹ lati lọ le Akintọla pada lọ si ilu rẹ.

Ọpọ awọn agbagba lo ti dide lati pari ija yi, lọjọ alaruba ni nwọn yi ọjọ ipari ija na si.

ADVERTISEMENT NO. 76.

**KERE O**

**OFIN TI A NFI NA OWO ATIJỌ (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS) DI PI PARE**

A fẹ la ti ran gbogbo ẹnyin enia leti wipe ati ọjọ kini oṣu July, 1962 (oṣu keje ọdun yi) gbogbo owo Atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Ṣile titi de ori Epini yio kuro. A ko ni le lo wọn gẹgẹ bi Ofin ni ilẹ Naijiria.

Eyi ni wipe lati ọjọ kini oṣu keje (July) ọdun yi, owo Atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun Iṣẹ Aje ni jake jado ilẹ Naijiria - fun apejuwe, aikoni gba fun Ọja rira tabi fun Ọja tita ninu Ọja ati Ṣọbu.

Gbogbo ẹniti o ba ni owo Atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni pepa tabi ni Ṣile ni lati tara lọ se paṣi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti Central Bank ti Naijiria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin, ti a si na lọwọlọwọ yi ki ọjọ kini osu keje ọdun yi (July) to to. Ofẹ ni gbogbo Bank yio parọ owo wọnyi fun yin.

*JOHN BEACH*
*Deputy General Manager.*

*Central Bank of Nigeria,*
*Lagos.*

**Ẹ ku ipalẹmọ ọdun**

# Ọrọ Olotu

## EDI TABI ẸFỌN

### Awolọwọ. Akintọla?

LẸKAN SI A TUN NI IDI LATI KE SI NYIN PẸLU IBERE YI: A GBỌ WIPE OJO IJA MIRAN TI ṢU LARIN NYIN. A MỌ OHUN TI EYITI Ẹ JA KOJA FA SILẸ, O SI DUN GBOGBO WA PE Ẹ KAṢỌ LORI ẸGUN.

Ti ojo yi ba ro, laiye ni ẹ o ma gba ire gbogbo wa ṣugbọn ti ojo yi ba rọ, boya on ni yio sin oku ilẹ yoruba nipa ilu ṣiṣe.

A bọ ọrọ la nsọfun ọmọ lawabi, nitori Ọlọgbọn ati Oloye ni yin.

AHỌN ATI ẸNU NJA

Ṣebi Igbagbọ tilẹ ni ẹnyin mejeji? njẹ ẹ o le dariji mẹkunnu ti o ba ṣe nyin bayi? ẹnyin ni olori ẹ fun wa ni apẹrẹ rere.

Naijiria yi nfẹ lo ẹnyin mejeji ni apapọ Iwọ Orun ko le fi Iyin silẹ nisisiyi Tọmọde Tagba lo ni Ireti ninu nyin.

Ẹ jọwọ ti ẹ ko ba tori iṣu jẹ epo ẹ tori epo jẹ iṣu, Efọn ki fọn omi, edi ki di ẹfufu. ẹ ma jẹ ki edi mu wa.

## Gbogbo rẹ Gbogbo rẹ

Ni ipade Sinodu ti awọn Sẹmẹsi ti nwọn ṣe l'Eko, bisọbu ni awọn onigbagbọ nkere si lojojumọ.

Anu ṣe ni lati gbọ eyi papa nigbati o jẹ lati ẹnu Bisọpu gan lo ti jade. Ṣugbọn ki o to jade lẹnu ẹni ewọ Howells, o fẹrẹ lo jẹ pe ko si ẹnikan ti ko mọ otitọ yi.

Kini o wa fa eyi? Ibere yi ni ki ẹni ọwọ Howells mura lati dahun tabi wa idahun si. Ti o ba ṣe eyi nigbana ni yio mọ ohun ti a o ṣe lati ma ni onigbagbọ si i.

Awọn ibere ti yio tubọ ran bisọbu lọwọ lati dahun ti akoko ni eyi.

1. Njẹ awọn Alufa ki isalọ fun abo lọdọ awọn onimale

2. Njẹ awọn Alufa ki iṣe ẹgbẹ oloriṣa ni oriṣiriṣi?

3. Njẹ Bisọbu ro pe Imale ti olori onigbagbọ nba fun iṣora yio di onigbagbọ?

4. Njẹ o ro pe oloriṣa ti olori onigbagbọ nba ṣe ẹgbẹ ti o si nfun ni ọwọ yio tun fẹ di onigbagbọ?

5. Njẹ bisọbu ro pe awọn 'mẹkunnu' ninu Ijọ yio ma fi tokantokan ṣe igbagbọ nigbati Alufa ba nfi ṣira da ijọ ru, ti o nfi ojukokoro ko owo jẹ, ti o nfi ẹmi eṣu so ogun mọ ara wasu, ti o si npa ogede lori igi.

Ẹ jẹ ki a yẹ ara wa wo awa onigbagbọ.

GBOGBO RẸ, GBOGBO RẸ LỌWỌ WA, ANI LỌWỌ ẸNYIN ALUFA, OLORI LO WA.

---

## MO YỌ FUN Ọ: IROHIN IMỌLẸ. KU ORIRE O!

Mo ki Olotu Irohin Imọle Ogbeni E. A. Adeniji pe o ku orire ti iwe re ohiyin momo ti o pe odun mefa ti o nti jade, fun Akoko re to re ti ore to koja.

Olowa yio tunbe [illegible] yio lowo o. O ni si te, Oho Oba ko ni si yin lese, Iwaju lopa Ebiti ure si iwaju ni e o ma lo.

— LATIFU BABALỌLA
AKỌWE AGBA ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

# Yẹyẹnatu!

## Ọ NI YẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:— Olotu, ọrẹ nyin ma wa nile Ọlọpa.

Olotu:— Ọrẹ mi wo ni yẹn?

Yẹyẹnatu:— Meji ni wọn?

Olotu:— Meji lawọn wo? A ni ọrẹ mi wo lo wa nile Ọlọpa?

Yẹyẹnatu:— Ẹ jọwọ ẹ ma kigbe mọ mi o jare, Igbalọ jẹ awọn meji lo wa nile Ọlọpa.

Olotu:— Wo o, to ba mọ pe o ko lọrọ sọ, kuro niwaju mi.

Yẹyẹnatu:— Ẹ tẹk risi kẹ, Ẹnyin na ẹ lọ ba awọn ọrẹ yin sọrọ kobinrin ma pa wọn.

Olotu:— Wo o, mo nsọ fun ọ Yẹyẹnatu ko gẹraotu.

Yẹyẹnatu:— Suberu ati S a m u wa ni Tesan Ọlọpa.

Olotu:— Ṣe o tan?



Yẹyẹnatu:— Ha! nwọn ti ro ẹjọ kan nyin, Ọlọpa si m b ọ wa ba nyin.

Olotu:— Hẹn, ko ma bọ.

Yẹyẹnatu:— O dara. ṣe ẹnyin fẹ gbọ ohun to faja sa?

Olotu:— To ba ni wes taimu mi.

Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ ranti orin ti Samu ni ki nwọn ma kọ fun on lọjọ ti o nṣeyawo?

Olotu:— Orin wo ni yẹn?

Yẹyẹnatu:— Ẹ ma le tete gbagbe nkan tabi Họsitẹ na lo nda nyin lamu to bẹ?

Olotu:— A! hẹn! Ṣe "Mọ ti gbọrọ kan nwọn nleri, nwọn lawọn o gbaya wa, ko le ṣe ṣe, ko le ṣe ṣe, ko ṣelẹpọn na. To jẹ jọṣẹ."

Yẹyẹnatu:— Iyẹn lẹ ni ẹ ko mọ. On ni yẹn kẹ.

Olotu:— Kilo wa fa Tesan?

Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ gbọ pe nwọn ti gba Iyawo Samu na?

Olotu:— Ha! ha! ha! nko gbọ. O min pe o ti ṣelẹpọn na to jọṣẹ.

Yẹyẹnatu:— Wo o, ẹpọn rẹ tobi gan, ọsẹ to jẹ papa to mi ni iduro.

Olotu:— Ha! ha! ha! o ma ṣe o.

Yẹyẹnatu:— Ẹ mẹni to gba a?

Olotu:— Tani?

Yẹyẹnatu:- Telọ to nranṣọ fun Samu.

Olotu:— Ha! Obinrin ko ma lori o, kilo ri lara Ọkunrin yẹn kẹ?

Yẹyẹnatu:— Ẹpọn to ni na ni.

Olotu: Gẹraotu, t'enia ba nsọtọ wa ma ṣeyẹyẹ

Yẹyẹnatu:- Misita Durosotọ, Ẹ jọwọ o.

Olotu:- Ewo lo wa kan Suberu?

Yẹyẹnatu: Nigbati Samu lọ s ọ d ọ Suberu, Iyawo Suberu fun wọn ni o n j ẹ. Bi nwọn ṣe jẹun tan ti Suberu ni ki on ble r e d i o fun Samu lo nkọrin Ayinde Bakare.

Olotu:- Ewo?

Yẹyẹnatu: "Olowọ gbayawo ọlẹ"

Olotu:- Ha! ha! ha!

Yẹyẹnatu:- Ni inu ba bi Samu, lo ba fọ redio Suberu

Olotu:- Olowo gbayawo ọlẹ, ha! ha! ha!

Yẹyẹnatu:— Ni wọn ba bẹrẹ ija, wọn da gbogbo adugbo ru kọlọpa to de.

Olotu:- Ewo lo wa kan mi?

Yẹyẹnatu:- Ti nko ba deru ba nyin bẹ bawo le ba ṣe k ọ t i si mi, igbati ẹ ti binu?

---

## Awọn enia meji ku sigboro Mẹka

JIDDA:- A gbọ wipe ni gẹrẹ ti awọn Alhaji ti o lọ gbẹhin gunlẹ si ebuto Jidda ni nwọn mu iro wa fun Alhaji Ahmadu Rufai wipe awọn meji ninu awọn Alhaji to wa lati Ilẹ Naijiria ṣalaisi, ọkan ku silu Mẹka ekeji ku si Medina.

Ninu irohin ti a gbọ, a gbọ wipe, awọn mejeji ti o ku na jẹ a r a Ilẹ Hausa. A koiti gbọ orukọ awọn Alhaji na.

# IFẸ LOJU (APA KẸFA)

Mo ripe gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin-Imọlẹ ranti ibiti mo ba itan mi yi de ni ọsẹ to kọja, emi yio bẹrẹ apa-kẹfa rẹ loni, gẹgẹbi mo ti sọ lọsẹ tokọja pe emi yio sọ bi iwa Muli tiri.

Niti iwa, ọmọ dada ni Muli nṣe, Ifẹ ọkọ rẹ si pọ lọ-kan rẹ. O mọ itọju ọkọ, o si mọ itọju ile, o yẹ 'palọ' o yẹ ni iwaju o si yẹ ni lẹhin, ṣugbọn ọmọ ti a fi ọla tọ ko ni ṣe alaima hu iwa ọla. Gẹgẹbi gbajumọ ati aye Ojogẹ, ọpọlọpọ Ile-Itaja Oyinbo-Oniṣowo ni nwọn ti mọ, o si ni iwe Igba-Ẹru pe-pe-pe lọwọ wọn ni awin,

LATI ỌWỌ

Afolabi Olabimtan

Anfani ti o wa ninu iru iwe yi nipe yio gba ẹru la-wio, yio si san owo rẹ ni ipari oṣu laisi ele. Ojogẹ ko fi ohunkohun pamọ fun Aya rẹ, o si gbe iwe yi le-e lọ-wọ, ṣugbọn ti Ojogẹ ba ti lọ si ibi iṣẹ, Muli na yio mu iwe yi, yio lọ fi gba ẹru yio si t a a yio jẹ ere, ti ọkọ rẹ ba si de, Muli a ko ere silẹ a si sọ fun bi on ṣ e ṣ e gbogbo rẹ nipa ṣiṣe eyi, Muli wa iṣẹ fun ara rẹ, owo nwọle fun. o si nsan owo pada si Ile-Itaja Oyinbo ni Ipari oṣu, pẹlu ere ọja nwọnyi. Muli nda aṣọ, ọ si nfi owo pamọ; ko si nwo ọwọ ọkọ rẹ kio to ra ohunkohun.

Eyi mu ọkan awọn mejeji balẹ daradara; ọtun nwẹ osi, osi nwẹ ọtun gbogbo ọwọ si mọ. Lẹhin ọdun kan gere ti nwọn ṣe Iyawo nwọn bi ọmọ-kunrin kan, nwọn si sọ ni Bọlaji. Bọlaji jẹ ọmọ-dekunrin ti o dara pupọ, bi o ti ndagba si bẹni ofi nni iteriba si, bẹ si ni gbogbo aladugbo si fi nfẹran rẹ si, orire ni Bọlaji ba wa si aiye nitori ọjọ ibi rẹ ni Iya M u l i wọ ile ọkọ ọmọ rẹ. Ṣe okun ibi rọ; bi ọgẹdẹ dudu ko ya bu ṣan ọmọ buruku ko ya lu pa. Iya Muli ko gbagbe ọjọ Ikunlẹ, ko ṣai ranti ọjọ atorunbọ abiyamọ, ọjọ Balaji de aiye, o ki Muli ku ewu. Ọjọ Muli di Iya-ọmọ, o ba Ojogẹ yọ, o si sọ ọmọ ni Ọmọlaja, ṣugbọn eyi ko wu baba Muli lori, ṣe ọkan Ọkunrin sa le ju ti Obinrin lọ.

Ni ti ẹtọ, o ranṣẹ lọ yọ fun Muli ṣugbọn o ti bura pe on ko ni ohunkohun lati baa ṣe ni iwọn igbati o ti doju ti on larin Ilu, Ju gbogbo rẹ lọ o ti kilọ fun Muli pẹlu Iya rẹ pe on ko gbọdọ ri awọn mejeji papọ ni ile on. O ni on ko kọ fun Iya Muli lati ma wa ọmọ rẹ wa bẹni on ko si le aya on n i n u ile on, ṣugbọn on ko gbọdọ ri ẹsẹ Muli ninu ile.

Bayi ni iya Muli ṣe bẹrẹ si wa Muli lọ si ile ọkọ rẹ. Tọkọtaya ti nwọn fi mọ ọwọ ara wọn daradara t o b ẹ ti ifẹ fi bo wọn loju, tobẹ ti nwọn ki iri ohun aidara kan lara arawọn di ẹniti o nwo arawọn lawo moju. Iya iyawo de, o fa ijọngbọn yọ, ana wole, rudurudu de, ṣe gbogbo ohun ti Muli ko ka si ri ni iya ntu pẹnpẹn. Iya Muli ko lọkan, ko tun gbọ Tọkọ mọ, ana wọle, o nforo ẹmi ọkọ. Ni akọkọ Muli ko mọ pe ohun buruku ni iya on nse, ko mọ pe Ile awọn ni iya fẹ fọ, bẹ ni Igbona ara ni iya fi nhuwa. "Ki Ọmọ mi ni Igbadun, ki Ọmọ mi Ọla ni Idẹra" iya gbagbe pe bakan ni awọn mejeji ti se ngbe ni Irẹpọ pẹlu inu didun ki on to de, Iya gbagbe pe diẹ ni o yẹ ki ti on jẹ larin Tọkọ-taya, o ṣa nja o ni, on nfẹ ki Ojogẹ ni ifẹ ọmọ on.

AKIYESI: Kini Iya Iyawo sọ fun Ọkọ ọmọ rẹ? Kini Esi Ojogẹ? Bowo ni Iya Muli se nṣe si Ọkọ Ọmọ rẹ? Ma se ṣa lai ma ka nipa rẹ lọsẹ to mbọ, nitorina tọju kọbọ meji rẹ silẹ lati fi ra IROHIN IMỌLẸ

## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra iwe IROHIN-IMỌLẸ fun kika tabi o nfẹ polowo Ọja sinu rẹ tabi o ni ẹrọ lati sọ nibi-kibi ni agbegbe Dahọmi, Wẹmọ, Igerefe, Ajaṣẹ, Abomi-Kalafi Mahin tabi Mẹkọ, ki o lọ si odo
MONSIOR L. M. ADESIYAN ILE IFIYE, ONIFAJI
PORTONOVO DAHOMEY

## Ewu lọ lori Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ kan ti o bọ sọwọ Oni jibiti

Mushin:- Irohin kan wipe awọn Oni jibiti fi ara wọn joye gun jile si ile pẹtẹsi kan to wa ni Osoni Street ni agbe-gbe Mushin.

Nwọn ri ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye kan ti o gbe Apo dani, nwọn rope owo lo gbe dani Ọpẹlọpẹ awọn Ọ,uinmọ ti o tẹle ọmọ Ẹgbẹ na lẹhin, nwọn ti mu wọle.

Ọkan ninu awọn Ọkunrin ti o tẹle Ọmọ Ẹgbẹ na lẹhin ti o mu fere Ọlọpa dani ibẹru bojo rẹ ko jẹ ki nwọn ṣe jibiti fun ọmọ Ẹgbẹ na.

## Wọn ji Awamọto kan gbe ni Ilu Oyinbo

LONDON:— A gbo Irohin wipe Okunrin kan ti o nṣe awo-moto nilu Oyinbo ti o si nwa moto ti o ko Ẹru Bans ti owo re to Egberun medogun Poun ni awon Olosa gbe ti nwon si lo so ho si ara Igi kan ninu igb o ti a npe ni Epping Forest ni Wanstead ni Ilu Londonu.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

RICHALET

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọm Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.
Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri, ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn se e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ile yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawẹnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti a w ọ n Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọn yi le se ọ Lakuregbe, orisirisi Ina-run, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdi-Jẹdi, Akọ Iba, arun Ẹdọki, Aya didun, Tanpara ati Ekuru laya.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi Ibaradi riro p ẹ l u egbogi Riṣaleti a ma pa gbogbo kokoro buruku ti o wa n i n u Ejẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran p ẹ l u nigbakugba.

Bere ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine tores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADELUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 2287

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI SOBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA

## Ẹnikan pa ọmọ ile Ẹkọ o si tun pa Ẹlẹmu kan

Ọmọ ilewe Aguda kan nilu Umuahia ni a gbọ wipe ẹnikan wo o ṣunṣun o si fi ada bẹ lori ni ọsan gangan bi ọkunrin na ti siṣẹ buruku yi tan beni o ri ọkunrin kan ti o nbẹ ẹmu lori ọpẹ ti oruko rẹ njẹ Peter Onwuyirika.

Ọkunrin kan ti o njẹ Ndidi, Alagba bayi to gbidanwo lati ra ọkunrin apania yi mu ni ọkunrin apania na ti o ti ya giripa tun ṣa ni ada yana yana tobẹ gẹ nṣe ni nwọn gbe lọ sile Iwosan ni ilu Umuahia.

Agbọ wipe baba Ẹlẹmu yẹn ni ọkurin na kọkọba lori ọpẹ, o wa duro de nisalẹ, bi o ti sọkalẹ ni ọkunrin na ba ṣa ni ada lojiji, lẹhin ti o pa tan o wa joko nibẹ, o mu ẹmu ti ọkunrin na gbe sọkalẹ o tun pọn ada rẹ daradara, nigbana lo to wa bẹ si oju ọna mọto, ki o to wa pade ọmọ ilewe Aguda, o si bẹ lori kege.

Iya ọmọ na sọ fun awọn Oniwe Irohin wipe, lọjọ na, on pẹlu ọmọ on lo jijọ npada bọ lati ọja, ki ọkunrin Apania to fo sojn ọna ti o si bẹ ọmọ on lori. Iya na sọpe on tilẹ bẹ Ọkunrin na kio kuku pa on pẹlu, ṣugbọn o kọ, o bẹ sinu igbo o si salọ.

Nigbati awọn Ọlọpa gbọ irohin yi, Ọga Ọlọpa kan dide, o si ko awọn Ọlọpa ṣodi pẹlu ohun ija nwọn bẹ si inugbo, nwọn nwa Ọkunrin Apania na ọwọ wọn ba ẹnikan, awọn Ọlọpa si mu lati wadi ọrọ lẹnu rẹ. Lẹnu rẹ ni awọn Ọlọpa si wa, nwọn nṣe iwadi ọrọ na lọwọ.

## Mufutau Adeniji ku sinu mọto to ṣe jamba

Ọmọde kan ti ko ju eni odun mejidilogun lo ti o nje Mufutawu Adeniji ti o nṣe ṣe atonisọna Ẹro gbohun-gbohun (Telephone) ni a gbo wipe o ku sinu moto kan ti o ṣe jamba loju Ọna Ijebu ni Akarigbo Street, nwon si yara gbe lo sile Alaisan ni Shagamu Hospital.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

"UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ehin didun eri ile itọ tabi itọ-jijo enia, itọ rirun, rakuruku Pipọn rirun, lakuregbe, iboradi wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ, Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹ bidan yi y.o wo san lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ kosi ni ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbirọbi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba a rara o! Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹjọ abo 8/6d owo Ọkọ Ṣile meji abọ (2/6d) Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI ṢỌBU IBADAN:-
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



# ṣile kan perè ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




**Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nibikibi nibikibi. Ṣile kan pere ni owo rira rẹ, bore egbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nibikibi, enikeni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura silẹ. Ra pakẹti "ASPRO" titun oni ṣile kan loni!**

# 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

Ẹnikẹni ti o ba ni mimọ ọjọ ibi rẹ, ki o lọ ṣe ayẹwo re awọn asọtẹlẹ Inu iwe yi, yio ri asọtẹle ọkan ninu awọn ohun ti yio ṣẹlẹ si ọ larin ọsẹ yi.

Jan 20 – Feb 18 (Aquarius) Maṣe fi ọwọ ara rẹ fa Ijọgbọn larin ọsẹ yi nitoripe ire kan sunmọ ọ pẹki pẹki

Feb 19 – Mar 20 (Pisces) Ohun kan ti o ti nle pa ti pẹ yio tẹ ọ lọwọ maṣe jafara lati rin sunmọ awọn enia Pataki.

Mar 21 – April 19 (Aries) Akoko to fun ọ lati pinnu gẹgẹ-bi iwọ yio ti ṣe ninu irin ajo ti mbọ wa ṣẹlẹ fun ọ laipẹ.

April 20 – May 20 (Taurus) Alejo kan mbọ wa yoju si ọ nitorina ki o mura lati fi gbogbọ ara ṣe lalejo.

May 21 – June 20 (Gemini) Ṣọra pupọ ninu ọsẹ ki ọrọ ẹnu rẹ ma ba da rogbo diyan silẹ.

June 21 – July 20 (Cancer) Ọjọ kan ninu ọsẹ yi, iwọ yio ba ohun ayọ pade ti ire yio si to ọ lọwọ.

July 21 – Aug 22 (Leo) A ti mọ pe ohun gbogbo ni iwọ ni itẹlọrun si ti iwọ ko si mbinu Ṣugbọn ọrọ kan yio ṣẹlẹ si ọ ti yio gejiya ẹmi rẹ iwọ ko gbọdọ binu tabi kọ o ja.

Aug 23 – Sept 23 (Virgo) Fi iṣẹ silẹ fun Igba diẹ larin ọsẹ yi ki o si gba atẹgun kakiri agbaiye.

Sept 24 – Oct 22 (Libra) Ṣọra pẹlu obinrin larin ọsẹ yi nitoripe awọn to ni fẹ rẹ ko ni fi ọ silẹ pẹlu iṣeku ṣe tabi ki o yan ale.

Oct 23 – Nov 21 (Scorpio) Ṣọra rẹ ki o ma ba dawọle ohun ti o le ju ọ lọ nitori iṣẹ atata mbọ wa yọju si ọ.

Nov 22 – Dec 21 (Sagisttarius) Ọrọ kan mbọ wa ru ọ loju larin ọsẹ yi Ṣugbon Inu awọn Ẹlẹgbẹ rẹ yio dun si.

Dec 22 – Jan 19 (Capricorn) Akoko owurọ ninu ọsẹ yi ko ni jẹki nkan bẹṣuọ fun ọ Ṣugbọn adun ni Igbẹhin.

# Ara Ọffa pe Ijọba Ibilẹ Ilọrin lẹjọ si Kọtu

ILỌRIN:- Ọkunrin ara Ọffa kan ti nwọn npe ni Oseni Jide, ti iṣe Alagbẹdẹ Wura lo pe Ijọba Ibilẹ Ilọrin ni ẹjọ si Kotu o ni ki Adajọ ba on gba Ẹdẹgbeta Pọnun lọwọ wọn fun on ati lọwọ awọn Onişẹ Ijọba mẹta nwọnyi:- Salami Aderibigbe, Buramọ Akanbi ati Ibrahim Ilọrin fun dida ti nwọn da on duro lọna ti abosi ti nwọn si gbe on ju si Ẹwọn laijẹbi.

Oseni sọpe, awọn Ọlọpa wa mu on nilu Ọffa losi Ilọrin, nwọn ju no si Ọgba Ẹwọn fun Ogọta ọjọ laijẹ pe nwọn fi iwe agbara mu on tabi nwọn ba on ṣe ẹjọ. Nitorina ki Adajọ ba on gba £500 ati £10 owo irin ẹsẹ

Ọgbẹni J. M. Adeṣiyan sọ fun Adajọ pe bawo ni enia ṣe ni lati gbe ọjọ meji ni Itimọlẹ laigbe de waju adajọ, nitorina ki Adajọ gba ọrọ on Oseni yi nitori ki awọn Ọlọpa le mọ iṣẹ wọn.

# Awọn ara ilu Uyo da ẹgbẹ Awo kan silẹ

UYO:- Agbo irohin wipe awon ara ilu UYO ati apa Ona Kalaba da egbe Awo kan Sile eyiti a gbo pe ipinnu egbe na ni wipe ki nwon ma yo kelekele lo se jamba fun enikeni ti ko ba fara mo ohun ti gbogbo ilu nfe.

Eyi ni ohun pataki to mu awon ijoye enia, igbimo nla ati kekere kigbe lo ba ijoba wipe, ki nwon tete ba won tete bo oro na. Ogbeni Akpabio ati Oloye Nyong so wipe, egbe N. C. N. C. ko gba fun enikeni lati ma lu iwakiwa si egbe N. C. N. C. ni agbegbe UYO IKOT EPENE ati NYONG.

# Ole ba Ole ninu oko

Lati Ọwọ:- AJẸGBORO DAGBA

Mo ki gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ kakiri ilẹ Naijiria, ẹ si ku a ba yọri ti enia kika nilẹ wa, Inu mi dun pe gbogbo wa ni a ran awọn Oluka enia na lọwọ ti o fi yọri si rere, Oluwa yio ṣe Ominira ilẹ wa ni omi idẹra fun enikankan wa nile ati loko.

Bi mo ti nlọ lọjọ Aje ni dede agogo mẹwa owurọ ni opopo Idunmota ni abẹ iboji agogo Bawa ni mo gbe ri awọn Ọmọdekunrin marun ti Ọgbẹni kan nyẹ apo wọn wo, mo ba ya bara lati wo ohun ti o fa ti o fi nyẹ apo wọn wo, a ṣe ọmọ gbe wiri ni wọn tun ja Ọga wọn lo le, wọn gbe ohun ti on na ji gbe mọ lọwọ, nigbati Ọmọbinrin kan nrekọja lọ lẹgbẹ A g o g o yi o si gbe owo pupọ dani lati lọ fi ra ọja lẹhin Ọgba owo yi ni Ọga awọn Ole yi ji gbe mọ obinrin na lara lai mọ ti o si sure gbe fun ọkan ninu awọn ọmọ ẹhin rẹ ti wọn si tun gba mọ on na lọwọ, o wa nyẹ apo wọn wo, ṣugbọn ẹ pa ko boro mọ, nwọn ti gbe pamọ.

Gbogbo igba ti mo fi duro lẹgbẹ ọdọ wọn, nwọn ko mọ pe mo ngborọ wọn ni, nwọn ro bi mo nduro de enia ni, nitori ko si ẹnikankan ti o jẹ Ajeji ti o ju emi lọ, nwọn ko mọ pe mo ngbọ gbogbo ọrọ aṣiri ti wọn nsọ.

Nitorina mo bẹ gbogbo ẹnyin Ọnkawe mi ẹ jọwọ, ẹ ṣọra yin nibi agogo Tawa, awọn ọmọ agbe-wiri ni o njoko nibẹ o! Ologbo, ẹ ṣọra yin o! gbogbo ọmọ ti ẹ ba ti ri nibẹ Ologbo ni, Ṣokoto wọn ki delẹ, nwọn ki wọ bata, buba Lailọnu ati Ṣokoto Agadaṣi ni Ọga n w ọ n ma nwọ, ki nde fila o. Ẹ ṣọra yin nibẹ o!

Lọsẹ to mbọ ilu Mushin ni mo nlọ, mo nlọ ṣe iwadi ọrọ kan nipa awọn ti o fẹ lu Jibiti fun Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye kan, ẹ o ma ka ọrọ na lọsẹ to mbọ o ọ ku ipalẹmọ Ọdun I l e y a o. Ki Onikaluku ninu ẹnyin Ọknawe mi ti o jẹ Musulumi tọju ẹran ti emi Ajẹgbo-ro Dagba silẹ mo nbọ wa ile yin lọla o.

# ỌMỌ JAIYE JAIYE WỌ AṢỌ ASIKO



Ọmọge ti ẹ nwo ninu aworan yi jẹ ọkan ninu Ọmọ Jaiye jaiye ti ilu Gẹẹsi larin awọn aṣọ titun ti ile Dior, ti nranṣọ awọn Ọlọla ọmọ Jaiye Jaiye ati awọn Olowo ni ọmọ Jaiye jaiye yi ti ra ọkan.

Nisisiyi Iyawo Ajẹgboro dagba ati Yẹyẹnatu ti ranṣẹ fun ọkan ninu aṣọ ti a nwọ lọrun ọmọ J. J. yi.

# Abọderin ninu Igbo Ma-peran (Apa-Kẹfa)

LATI ỌWỌ:- ABUDULAHI A. AWELENJE
No. 1, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ibiti mo ba itan na de ni igbati ọmọ bọ lẹhin ọkan ninu awọn Obinrin ti nwọn nja, nigbati ọmọ yi bọ obinrin na ko tilẹ bikita, o kan nja lọ ni, nigbati ija si pari ni o ba gbe ọmọ rẹ, o si ri wipe o ti ku lo ba rẹrin, o si gbepọn, o si nṣọrọ lọ si ile. Obinrin Arẹwa kan sọ fun wa wipe jijẹ ni yio jẹ ọmọ na ati wipe on ati ọkọ rẹ ni yio jẹ. Lẹhin eyi a kuro nibẹ o di ile Ejọ wọn gẹgẹbi aṣa wọn nilu yi, ki nwọn to bẹrẹ Ejọ ṣiṣe, gbogbo ero iworan pata ni yio dide ni kọkan ti nwọn yio sọ ohun ti nwọn jẹ, ẹniti o ta fẹn wọn ati bi o ti se dun to lẹnu wọn ati iye ti nwọn ra bi o ba se sọ, bi nwọn ba si nsọ ọrọ oniẹ yi lọwọ, nwọn ko gba ẹnikẹni laye mọ lati wọ inu Ejọ ayafi bi nwọn ṣọ tan, ẹnikẹni ko si gbọdọ p'ariwo ni akoko yi.

Bi awa ti de ibẹ gẹgẹbi Alejo, awa ko mọ, obinrin ti o si mu wa lọ papa, ki ngbe arin ilu wọn, nitori wa ni o se fẹ lọ wo'ran nile Ejọ na, ko de ibẹ ri, bi a ti fẹ wọ ile, ni Ọba kigbe wipe "Ẹ MU WỌN!" ti awọn Oniṣẹ rẹ si ti yi wa po, nwọn ba mu wa, odi ile Ọba, nigbati a de ibẹ nwọn so wa mọ idi igi ijin nla kan ti o wa niwaju ile Ọba na, nwọn si nfi wa se yẹyẹ, bi nwọn ba ti nlọ, ati bi nwọn ba ti nbọ lati ile Ọba. Gbogbo ireba si ni a nri awọn enia nla ti nwọn nwa si ile Ọba lati wa bere igbawo ni pipa yia jẹ?

Lẹnu ọjọ diẹ, nwọn dajọ pipa wa si ọjọ kẹta bi a ti gbọ bayi inu bi mi mo si wi fun awọn iyoku mi ki wọn jẹki a sa ija wa boya a le bọ a sa ipa wa titi ṣugbọn ko bọsi ni gbati a sa pa yi gbogbo enia wa pe le wa lori nwọn nwo wa nwọn si nrẹrin inu tun nbi wa.

Nigbati o di ale nwọn tu wa lo si Agbala Ọba, nwọn lori kori koriko Elegnn, nwọn ti ilẹkun mọ wa. nigbati o di oru awọn ilẹkunṣi a jade, Ṣugbọn nwọn ri wa nwọn tun mu wa, Arikutaku si gun ọkan pa ninu nwọn, nibiti nwọn tun mu wa lọ, lẹnin na nigbati a wọ ibẹ fini fini a ri awọn irin ti ẹnu wọn mu ṣonṣo ṣonṣo nwọn pọ, a si mu ọkan kan atun awọn ohun miran ti a lero wipe o le ran wa lọwọ bi ija aja lọ sọrun ti a fẹ ja lọjọ kẹta ọjọ na.

A mura bayi tan, ni awọn iranṣẹ ọba ba tun ko Ẹgba de nwọn nna wa bi ẹran, titi a fi fẹrẹ ku ti ilẹ si mọ.

Lọsẹ to mbọ ẹ o ka ohun ti a ro lọjọ keji ati ohun ti a ṣe lọjọ kẹta. Ọlọrun ko ni fi kobọ meji tẹ ma fi gbadun itan mi yi titi yio fi tan owo ko ni wọn yin o Amin.

Ẹ ku Ipalẹmọ ọdun Ileya o Ọbẹ o ni ṣẹlẹ o.

# Igbimọ Synodu lodi si aṣọ Ebi ati aṣọ asiko

EKO:- Irohin kan wa wipe awọn Igbimọ Synodu ti nwọn ṣe Ipade Ẹlẹkẹdogun nilu Eko, gbogbo wọn lo si lodi si ọrọ aṣọ ebi ati aṣọ asiko, Ẹni ti a gbọ pe o damọran na silẹ ni Iyafin Ẹniọla Ṣoyinka, Ẹniti o si gbe e lẹsẹ ni Iyafin Erin Ọla Kutti.

Awọn meji wonyi lo rohin fun Igbimọ Synodu Iṣẹ buruku ti aṣọ Ebi nse larin awọn Ọmọ wa.

Awọn Igbimọ fi Oke le wipe ki Ẹnikẹni ko janu awọn tire ki nwọn maṣe lọwọ ninu aṣọ ebi bo tiwu ki owo rẹ kere to.

# Rogbodiyan bẹ silẹ Larin meji Ọgba Ẹwọn Nilu Zaria

KADUNA:- Ọrọ ko dun nigbati awọn Ọlọpa Ijọba, (Nigerian Police) ati awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ Dongari, ati awọn Dandoka fi nrọ girigiri lọ si Ọgba Ẹwọn nilu Zaria, ija na ṣẹlẹ larin meji awọn Elẹwọn ati Dẹrẹba wọn.

Ninu rogbodiyan na, Dẹrẹba Ẹlẹwọn kan ti awọn npe ni Riliwanu fi ara gbogbẹ gidigidi, ija na si pẹ jojo ki awọn Ọlọpa to bori. Ṣugbọn Riliwanu mbẹ ninu rojuje rojumọ ninu ile iwosan Zaria. Awọn ti o tun fara gbọgbẹ ni Imoru Disu, ati John Okoro.

Agbọ pe nigbati Olori awọn Dẹrẹba fẹ da si ọrọ na ibẹ ni awọn ti gun ni ọbẹ, gbogbo awọn Ẹlẹwọn to lọwọ ninu ija na mbọ ni ITIMỌLE.

# Erin inu Igbo tẹ Ọdẹ Omi kan pa

ANAM-: Ọkunrin Isobo kan ti o nṣe ọdẹ oju-omi ti o npa ẹja ni a gbọ pe Erin Ajanaku tọ pa si eti omi.

Bi a ti gbọro na si niyi wipe Ọdẹ omi na ri ẹja pupọ pa ni ọjọ na o wa lọ sinu igbo lati ṣe igi ti yio fi yan ẹja. Bẹni o ko firi ẹran Erin ti o mbọ wa, lo ba gbeṣi.

Nibiti o ngbe nsalọ, o ba sinu Itakun igi, ki o si to yanju ara rẹ tan, Akọ Erin ti ba, o si fi ọsẹ tẹ mọlẹ, o si pa Ọdẹ-Omi na.


GBANGBA DẸKUN!! KEDERE BẸWO!!!




PORAL

OLUBORI EGBOGI "IKỌ"

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubelọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwoṣan rẹ raro, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranse ti nwọn npe ni 'PORAL' ojulowo baunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ Fere, Ikọ Tutu, Ikọ ọna Ọfun, Ikọ Igba-aiya Ikọ-Lile, Ikọ" ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igba-aiya tabi ọna Ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun dadadara, iwọ yio si ma sun fọnfọn pẹlu Alafia ara.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣirisi Egbogi Ikọ miran ni ṢỌBU awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADELUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 2287

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI ṢỌBU IBADAN:-
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA


# OGUN ITAJA

## Ẹ ma polowo Ọja yin sinu iwe Irohin Imọlẹ ni gba gbogbo

## EWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

# Irọ npurọ funrọ

H—e—e
Mo tun de bi mo ti ma de o
Mo bọ bi ẹni a nfohun tere de
Ẹ wa gbọ bi Wale ṣe fAjile ṣaya
Ẹ wa gbọ bi'rọ se p u r ọ funrọ
Bole ṣe npajepo la ni Jaguda
Ajile lẹwinju, o dara lọmọ
Ajile nidi lyawo to fi nfanimọra
O ni eji ẹhin to fi npọkunrin ku
O ni ẹhin leke to fi nda wọn lọrun gidi
Ani bo ba wẹni tọba mi lẹwa ran
Yara wa Ajile
Bo nwẹni lẹwa ju nilẹ yi
Ko yara tọ Ajile lọ.
Gbogbo bọyisi lo nrele Ajile
Gbogbo ọmọge lo nsare le
Ajile layaya, o ya onisina
Ajile nwọkọ, o nsagbere
Ṣoju Ajile ko kuku gbe bi kanṣo
B'Ajile ba gba lọwọ onigba, a fi ranṣọ
A gba lọwọ alawo, a fi ra 'lẹkẹ
Ajile a gbowo lọwọ alaini a ya fi tun ra ṣe
Obọ njogẹdẹ, ọbọ nge di mọnu
Ọdẹ ko tete mọ pohun to ndun lo npaoi
Ọjọ Ajile ri Wale lọ ti rolufẹ
Ọjọ o ri Wale lo ti rọkọ
O ṣeleri pe, o l'on yio fẹ Wale
O ni bo ba ṣorun, ton rẹ la jọ nlọ
Ajile ri Wale, o fẹwa tan Wale
O ri Wale, o fi gbogbo ara fa mọra
Ṣugbọn Wale ma ti nfẹ Dupẹ ọjọ pẹ
Wale ti nfẹ Dupẹ ọjọ go
Sibẹsibẹ eyin oju Ajilo o npe Wale lẹjọ
Idi Ajile nawọ sọmọ ọlọmọ
Wale ṣera titi ara ko ṣe ṣẹ
O se'ra titi ara ko ṣe o jare
Lo ba p'Ajile o lon a fẹ
Awodi to nrajo, ẹfufu tá nidi

Ajile tun redi, o nreju sọmọ ọlọmọ
A! obinrin ni koto gbogbo wa
Ọjọ obinrin ba tan laiye
Ni bukata ọkunrin tan
Ọjọ o ba laya lo bẹrẹ adukiri
Ajile nfẹ Wale ko fi Delumọ silẹ
O nfẹ Wale ko gbagbe Olowu
On fẹ Wale ko gbagbe Adelani
O nfẹ W a l e ko gbagbe Adejare
Irọ npurọ funrọ. Ajepola npolopo2bo lole
Ṣewa Ajile lo nmu Wale
Idi timitimi lo nfọmọkunrin mọra
Tani jẹ faja ṣeyawo sinn ile
Tani jẹ faja ṣaya
Wale ko nawo fAjile
Gbogbo ohun to ni ti Dupẹ ni iṣo
Ajile ko nawo fun Wale
Ṣugbọn lọwọ Ọkọ ita lo ti ngbowo kiri
Wale ntoju Dupẹ, o ngbe Ajile
Ajile ngbe Delani o ngbe Olowu
O ngbe A m ọ o, o ngbe Adejare
Ṣe Wale lo nfọkan si
To fi ngbe gbogbo wọn
Ṣugbọn aṣorobo ni ṣina
Wale ti gbọ pe'gba l ọ k ọ Ọmọge
Wale ko binu, ṣọni a ko mọri iba ku
Nlọrọ Ajile, a fidi fanimọra
Ọjọ Iyawo Wale on Dupẹ lagan bọ
T'Ajile ṣomi loju poroporo
To ṣokun kikoro, to poṣe
O gahọn jẹ, o geku jẹ
Ṣugbọn ẹpa ko boro
Epe ilasa ko magbọrin o jare.
Ajile purọ f'Ajile
O purọ fun Wale
Wale punrọ f'Ajile
Nwọn jọ purọ fun'ra wọn.

AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

Ref. N° 55. PHOTO

Free illustrated catalogue on demand.



PRICE £ 5.

WINDSOR

19, Avenue de Lérins — Cannes, France

## Kaka ki Ebiti pa Agbonrin, o pa Adelebọ onile Ọlọna

NGWO:- Ọkunrin agbẹ kan ṣakiyesi wipe ẹran Agbonrin kan ma nwa sinu oko rẹ nigba gbogbo, nitorinbẹ, o dẹ E b i t i kan silẹ de Agbonrin na. Obinrin gbajumọ kan ti o njọ Mgbafor lọ si oko lati lọ ṣẹgi, bi o si ti nṣẹgi ninu oko, ko se akiyesi iwaju rẹ, be ni o kọlu ebiti Ebiti na si gbe la mọlẹ; o wa bẹrẹ si ke ibosi
Awọn enia ko tete gbọ igbe rẹ, nitori ibẹ jina si abulo wọn. Obinrin Akegbe kan lo npada bọ wa sile lati oko iwaju ti o si ngbọ igbe ọmọ-binrin na, o fi ara ṣoko o si rora noga wo ẹniti o nki gbe na. Nigbati o ri, o mọ ọ, o si sare lọ si Ngwo lati lọ rohin fun ọkọ rẹ Ebiti na ti bo gbogbo ara rẹ, nṣe ni wọn gbe lọ si Ile Alaiṣan nigboro Ilu Enugun.

Lẹhin na ni awọn Ọlọpa wadi ẹniti o dẹ Ebiti na, nwọn si mọ, nwọn da Agbẹ na duro lati gbọ ti ẹnu rẹ. Ọ r ọ na koiti pari sibẹ nitori a gbọ pe Obinrin na ko ni alafia.

## Oloye Okotie-Eboh fo lọ silu Oyinbo

Oloye Okotie—Eboh fo bi Ẹiye lọ silu Oyinbo, lati lo bere irin ajo Ogoji Ọjọ tio fe lo nilu Oyinbo. yio de R o m e, Britain ati Belgrade, ṣugbọn ọjọ metala ni yio lo ni London, bakan na si ni yio ba ijoba ile Oyinbo soro asiri ati nipa iṣe ti yio le se anfani fun ile Naijiria, nipa £676 million ti nwon fe fi tun ile Naijiria se.

## Ibrahim Wasiri Jalo



Ẹniti a nwo yi ni Malam Ibrahim Wasiri Jalo ti iṣe alaṣẹ Igbimọ House of Representatives o si jẹ ọkan pataki ninu awọn enia ti o wa pari iarin awọn oṣiṣẹ nilu Ibadan on lo duro ti o wọ ẹwu funfun ti o si sọkalẹ ninu mọto.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS
16' Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adenij
24, Oluyide Lstreet, Odu Abore MUSHIN.